# A RÁN APỌSTELI MEJILA JADE

## Matteu 10:1-42

## ẸKỌ 81 – FUN AWỌN AGBA

**AKỌSORI: "Nitori àjaga mi rọrun, ẹrù mi si fuyẹ" (Matteu 11:30).**

**Awọn Ọmọ-Ẹ̀yin di Apọsteli**

Ni ibẹrẹ iṣẹ-iranṣẹ Jesu, O ti yan awọn ọkunrin mejila lati jẹ́ ọmọ-ẹyin Rẹ̀ tabi awọn ti yoo maa tọ Ọ lẹyin. Wọn ti fi ile wọn ati iṣẹ wọn silẹ lati tẹle Jesu. Wọn ti wà pẹlu Rẹ̀ nigba ti O n waasu ni Ori Oke. Wọn wà pẹlu Rẹ̀ lori okun Galili nigba ti a dá igbi duro nipa ọrọ Jesu. Wọn ti ri I nigba ti O n ṣe ọpọlọpọ iṣẹ iyanu – a wo ẹlẹmi eṣu san, obinrin ti o fọwọ kan iṣẹti aṣọ Rẹ̀ ri imularada, a jí ọmọbinrin Jairu dide kuro ninu okú, ati ọpọlọpọ iṣẹ iyanu miiran.

Oriṣiriṣi iṣẹ ni awọn eniyan wọnyii n ṣe tẹlẹ -- awọn apẹja, awọn agbowo-ode, awọn ọmọ-ẹyin Johannu Baptisti -- ṣugbọn ẹkọ kan naa ni a kọ́ wọn lọdọ Jesu. Nisisiyii wọn o jẹ́ Apọsteli, itumọ eyi ti i ṣe "awọn ti a rán jade." A rán wọn jade gẹgẹ bi ẹlẹri tootọ lati waasu Jesu Kristi ati lati kọ́ ni nipa Rẹ̀. Ẹlẹri ni ẹni ti o n sọ ohun ti o ti ri ti o si ti mọ̀ nipa iriri ti oun tikara rẹ̀, ki i ṣe ohun ti ẹlomiran sọ fun un. Lẹyin eyi paapaa nigba ti wọn n yan Apọsteli kan lati dipo Judasi, wọn n fẹ ẹni kan ninu awọn ti wọn ti "mba wa rìn ni gbogbo akoko ti Jesu Oluwa nwọle, ti o si njade lãrin wa, bẹ̀rẹ lati igba baptismu Johannu wá, titi o fi di ọjọ na ti a gbé e lọ soke kuro lọdọ wa" (Iṣe Awọn Apọsteli 1:21, 22).

Jesu rán awọn ti o tọ́ lati jẹ Apọsteli Rẹ̀. O rán awọn ti wọn ti ni anfaani lati wà pẹlu Rẹ̀, awọn ti wọn ti kọ́ ẹkọ lọdọ Rẹ̀, ti wọn si ti ní iriri ti o daju pẹlu Rẹ̀. Lonii Ọlọrun ki i rán ẹnikẹni ṣá lati lọ tan Ihinrere Rẹ̀ kalẹ; O n fẹ awọn ti o ti ni iriri agbara Rẹ̀ lati lọ sọ nipa Rẹ̀.

O jù pe ki a kan maa wo Kristi nigba ti O n ṣe iṣẹ iyanu, nitori O fun awọn paapaa ni ẹtọ ati agbara lati lé awọn ẹmi aimọ́ jade ati lati ṣe iwosan gbogbo oniruuru aisan ati arun pẹlu. Ohun kan ni lati kiyesi iyipada ti o ṣẹlẹ ninu igbesi-ayé ẹni kan ti o di Onigbagbọ, ki a gbọ́ ki o jẹri, ki a si ri i ki o ṣiṣẹ fun Oluwa, ṣugbọn ohun miiran patapata ni lati ní iriri ati agbára Ọlọrun ninu wa.

Awọn eniyan wọnyii ti bẹrẹ si i maa tẹle Jesu, lẹyin eyi ni O pè wọ́n lati jẹ́ oniwaasu. Nigba ti a ba bẹrẹ irin-ajo wa gẹgẹ bi Onigbagbọ́, a kò mọ eto ti Ọlọrun ni ni ipamọ fun wa, tabi ipò ti yoo pe wa si. Ohun ti a le ṣe ni pe ki a sá gbọran, nigba naa a oo ni ẹri bi ti Paulu – "Emi kò ṣe aigbọran si iran ọrun naa."

**Aṣẹ**

Bi Jesu ti n rán awọn Apọsteli yii lati tan Ihinrere kalẹ, O fun wọn ni aṣẹ pato nipa ibi ti wọn yoo lọ, ohun ti wọn ni lati waasu ati bi wọn yoo ti waasu. Pẹlu awọn aṣẹ wọnyii O fun wọn ni awọn ileri, ikilọ, ati ọrọ imulọkanle.

Ni akoko yii wọn ni lati waasu fun kiki awọn Ju nikan, awọn ẹni ti O fi wé agutan ti o sọnu, ti o wà ninu ifebipa ti ẹmi ati ikú; nitori Israẹli kò ni oluṣọ-agutan. Lẹyin eyi, a sọ fun awọn Apọsteli lati waasu Ihinrere fun awọn Keferi. Jesu wi pe lẹyin Ọjọ Pẹntekọsti wọn yoo waasu ni Samaria ati ni opin ayé pẹlu.

Eyi ni yoo jẹ́ ọrọ iwaasu wọn: "Ijọba ọrun kù si dẹ̀dẹ." Eyi naa ni iwaasu ti Johannu Baptisti waasu, oun si ni iwaasu ti awọn alufaa wa n waasu lonii.

Wọn o lọ lati waasu ati lati ṣe imularada lai gba ohunkohun, gẹgẹ bi Kristi ti ṣe. O ti wi pe, "Ati funni o ni ibukún jù ati gbà lọ" (Iṣe Awọn Apọsteli 20:35). Oluwa sọ fun awọn Apọsteli Rẹ̀ pe wọn kò gbọdọ mú owó lọwọ tabi ipaarọ aṣọ paapaa nitori O mọ̀ pe ohun ara wọnyii yoo jẹ́ ẹrù ati idiwọ. Lonii ero owo ati ohun ini awọn ẹlomiran gba ọkàn wọn kan to bẹẹ ti Jesu ati iṣẹ Rẹ̀ fi wà ni ipò keji ninu ayé wọn dipo ti i ba fi wà ni ipo kin-in-ni.

Jesu sọ fun awọn ọmọ-ẹyin pe ki wọn duro ni ile ẹni ti o bá gbà wọn. Bi a ko ba gba wọn ki wọn lọ si ile ẹni ti o ṣetan lati gbà wọn. Wò o bi o ti buru to lati kọ Ihinrere ati lati dí itankalẹ rẹ̀ lọwọ! Boya awọn ti ko gbà wọ́n yii kò tun ni ni anfaani miiran mọ́ lẹyin eyi. A sọ fun awọn Apọsteli pe ki wọn gbọn ekuru ẹsẹ̀ wọn silẹ nigba ti a ba kọ̀ wọn ni ile kan tabi ilu kan. Wọn kò gbọdọ bá wọn wí, tabi ki wọn bẹ̀ wọn, tabi ki wọn ba wọn ṣe ariyanjiyan. Kò si ẹmi igbẹsan" tabi "ṣe mi n ṣe ọ" ninu Onigbagbọ́. Ninu Romu 12:19 a kà pe, "Oluwa wipe, Temi li ẹsan, emi ó gbẹsan."

**Inunibini**

Nigba ti Jesu rán wọn jade O wi fun wọn pe wọn ko le ṣai ni idojukọ. Gẹgẹ bi a ti ṣe inunibini si Jesu bakan naa ni a o ṣe si awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ -- gẹgẹ bi agutan laaarin awọn ikooko. Awọn ikooko jẹ́ ọta awọn agutan. Bi wọn ba ri aaye, wọn o pa awọn agutan wọn o si jẹ wọ́n. Lati atetekọṣe wá ati titi di isisiyii ni awọn eniyan Ọlọrun ní awọn ọta ti yoo pa wọn run patapata bi wọn ba ri aaye. Ọlọrun ti kilọ fun awọn eniyan Rẹ̀ ki wọn ba le wà ni iduro gangan ki wọn má si ṣe fi àye silẹ fun ọta lati pa wọ́n lara.

Nitori naa a sọ fun awọn Apọsteli pe ki wọn ki o "gbọ́n bi ejò, ki ẹ si ṣe oniwà tutù bi àdaba" Ninu Ọgbà Edẹni, Satani yàn lati lo ejò nitori o ṣe alarekereke tabi ẹranko ti o kún fun ọgbọ́n ẹ̀wẹ́ ati iṣefefe. A maa n fi àdaba ṣe apẹẹrẹ alaafia wiwà ati aileeri, ifẹ tabi iwa pẹlẹ. Adaba ki i pa ẹnikẹni tabi ohunkohun lara, kò tilẹ le daabo bo ara rẹ̀ paapaa. Ni ọna miiran pẹlu, a fi Onigbagbọ́ wé adaba. Gẹgẹ bi adaba ti mú ihinrere ti ilẹ ti o gbẹ wá fun Noa bẹẹ ni Onigbagbọ́ a maa mú ihin ayọ̀ ti Ihinrere wá. Olorin Sọlọmọni lo adaba lati ṣe akawe Ijọ ti o n reti bibọ̀ Kristi. A ti ṣe akiyesi pe adaba a maa yara gbagbe ipalara rẹ̀. Onigbagbọ́ fẹran awọn ọta rẹ̀ a maa ṣoore fun awọn

ti o korira rẹ̀, a si maa gbadura fun awọn ti n ṣe inunibini si i (Matteu 5:44). Gbogbo iwa wọnyii – aile pa ni lara ti adaba, ati ọgbọ́n ejo – ni apapọ ni wọn jẹ́ iwa Onigbagbọ́. Apapọ mejeeji yii ni Oluwa n fẹ ki awọn Apọsteli Rẹ̀ ni. Onigbagbọ ni lati sọrọ jade gbangba ki o si mu iduro rẹ̀ lai gbọjẹgẹ́ fun awọn ẹlẹṣẹ, ṣugbọn ki o sọ otitọ. Jesu sọ pe, "Otitọ yio sọ nyin di ominira."

Jesu kilọ fun awọn Apọsteli pe awọn eniyan yoo korira wọn, wọn yoo si mu wọn wá siwaju awọn onidajọ lati jẹ́ ẹjọ nitori wọn jẹ Onigbagbọ́. Ṣugbọn O ni Ẹmi Ọlọrun yoo kọ́ wọn ni ohun ti wọn o sọ.

**Aabò**

Ọrọ ikilọ wọnyii le ti mu ibẹru wọ inu ọkàn awọn miiran, ṣugbọn Jesu mọ akoko ti o tọ́ lati fun ni ni imulọkanle. O sọ fun wọn nipa itọju ati aabò Ọlọrun. Nigba ti a ba n ka awọn ọrọ iyanu ti imulọkanle yii, a n ranti pe ki i ṣe awọn Apọsteli nikan ni wọn wà fun ṣugbọn fun gbogbo awọn ọmọ-lẹyin Kristi. Gẹgẹ bi Ọlọrun ti mọ ohun gbogbo nipa awọn Apọsteli, bakan naa ni Ọlọrun mọ ohun gbogbo nipa wa. Irun-iyirun ori wa paapaa ni a kà pé ṣánṣán. A niye lori ju awọn ologoṣẹ lọ, awọn ẹyẹ ti a kà si ohun ti o wọ́pọ̀, ti kò niye lori lọ titi, ti kò si wulo fun ohun pupọ. Ṣugbọn ronu bi Ọlọrun ti n fi aṣọ bò wọn, ti O n pese ounjẹ fun wọn, ti O n daabo bo wọn, ti O n fi orin si wọn lẹnu, ti O si n kiyesi wọn bi wọn ba bọ́ silẹ. Ọlọrun ki yoo ṣe ohun ti o dinku si eyi fun wa.

**Jijẹwọ Kristi**

Lati jẹwọ Kristi niwaju awọn eniyan ni kọkọrọ si ati ni aabo Ọlọrun, nipa ti ẹmi ati nipa ti ara. O ṣe pataki ju ohun ti a le gboju fò tabi ṣe aibikita nipa rẹ̀ lọ. On -- jijẹwọ Kristi niwaju awọn eniyan – ni yoo fi hàn bi Jesu ba ti jẹwọ awa paapaa. Ọna pupọ ni o wà lati gbà fi jẹwọ Kristi: a ni lati jẹri niwaju awọn eniyan, ṣugbọn eyi nikan kọ́. Awọn ẹlomiran le sọrọ ti o dùn pupọ ṣugbọn igbesi-ayé wọn ojoojumọ tako ọrọ wọnyii. Bakan naa lati sẹ́ Jesu ju pe ki a tako Kristi niwaju awọn eniyan. Lati kọ̀ pe ki Jesu wọ inu ọkàn, lati dá ohun kan duro lai le fi fun Ọlọrun, lati sẹ Ẹ ati iṣẹ Rẹ̀ -- gbogbo wọnyii ni a n pè ni sisẹ Ẹ. Kò ṣe e ṣe fun ẹni kan lati di Onigbagbọ́ ni kọrọ ki ẹnikẹni má mọ̀. Ni ori keje Matteu a sọ fun wa pe, "Igi rere ko le so eso buburu, bẹ̃ni igi buburu ko si le so eso rere. . . . Nitorina nipa eso wọn li ẹnyin o fi mọ̀ wọn."

**Awọn Ọta Eniyan**

Jesu sọ fun wọn pe o ṣe e ṣe ki Onigbagbọ ni idojukọ lati inu ẹbi rẹ̀. Awọn ti a gbà là ninu ẹbi a maa gbé igbesi-ayé ti o yatọ si ti awọn mọlẹbi ti a kò gbà là. Obi ti a kò gba la le doju ija kọ ọmọ ti o jẹ́ ẹni iwa-bi-Ọlọrun; nigba miiran ọmọ ti ko i ti i ri igbala ni yoo doju ija kọ obi ti o jẹ́ ẹni iwa-bi-Ọlọrun. Ifẹ ọkàn wọn ki i ṣe bakan naa mọ̀, bẹẹ ni ko le si iru irẹpọ ti o ti wà laaarin wọn tẹlẹ rí. "Nitori ìdapọ kili ododo ni pẹlu aiṣododo? idapọ kini imọlẹ si ni pẹlu òkunkun?" (2 Kọrinti 6:14).

Pẹlupẹlu a maa n fẹran awọn ẹbi wa lọpọlọpọ. Ṣugbọn Bibeli sọ fun wa pe a ni lati fun Ọlọrun ni ipo kin-in-ni ninu ọkàn wa. Nitori naa a ni lati yàn – lati fẹ Ọlọrun pupọ jù lọ, tabi lati fẹran ẹbi wa tabi ẹni kan ninu wọn ju Ọlọrun lọ. Bi a o ba jẹ́ ọmọ-ẹyin Kristi, Oun ni lati wà ni ipò kin-in-ni ninu ayé wa. "Tani yio ha yà wa kuro ninu ifẹ Kristi?" (Romu 8:35).

Lati ru agbelebu, ju pe a n fi ara da idanwo nitori Ihinrere. Itumọ rẹ̀ ni lati mura tán lati fi akoko wa fun Kristi ati lati ṣe iṣẹ isin wa ni ipa ti Kristi. Gẹgẹ bi o ti ri loju ayé, eniyan ti sọ ẹmi rẹ̀ nù nigba ti o ba jọwọ rẹ̀ fun Ọlọrun fun iṣẹ-isin atọkanwa, nigba ti o jẹ pe o ti jere iye ainipẹkun. Eniyan kò ni ẹtọ si ibukun ati anfaani ifẹ Ọlọrun ayafi bi o ba fi ayé rẹ̀ fun Un.

Ki i ṣe pe Onigbagbọ́ n gbé agbelebu rẹ̀ nikan oun a tun maa tẹ̀le Jesu pẹlu. Adura tabi ifararubọ rẹ̀ ni: "Lati ṣe ohun ti O fẹ ki n ṣe, lati jẹ́ ohun ti O fẹ ki n jẹ́, lati lọ si ibi ti O fẹ ki n lọ ati lati sọ ohun ti O fẹ ki n sọ." Gẹgẹ bi Peteru, eniyan le fi gbogbo rẹ̀ silẹ lati tẹle Jesu, ṣugbọn koko ti o wà nibẹ ni lati jẹ́ oloootọ ki a si tẹle E titi de opin. Jesu ni "Ẹniti o ba foritì i titi fi de opin, on na ni a ó gbalà" (Matteu 10:22).

**Èrè**

Gẹgẹ bi a ti ṣeleri èrè fun awọn Apọsteli oloootọ bakan naa ni a oo fun wa ni èrè fun iṣẹ́ ti a fi otitọ ọkàn ṣe fun Ọlọrun. Ninu ayé yii a maa n ri igbadun ati itẹlọrun pupọ ninu iṣẹ Oluwa, ṣugbọn ki i ṣe bẹẹ nikan. Ni Ọrun a oo pín èrè – ki i ṣe fun iṣẹ́ nla, ṣugbọn fun ijolootọ. Ohun ti awọn Apọsteli ti itori rẹ̀ sin Ọlọrun gan an naa ni idi rẹ̀ ti awa pẹlu fi n sin Ọlọrun lode oni. A fẹ́ lati sin Ọlọrun nitori ifẹ wa si I, ki i ṣe fun iyin eniyan tabi fun èrè.

## AWỌN IBEERE

1. Ta ni rán awọn Apọsteli jade?
2. Ki ni ṣe ti O fi agbára fun wọn?
3. Ta ni a rán wọn sí?
4. Ki ni wọn waasu?
5. Ki ni ṣe ti a ni lati jẹwọ Jesu niwaju awọn eniyan?
6. Darukọ awọn Apọsteli mejila lati ori.